# OMI, MANNA ATI APARO

## Ẹksodu 15:22-27; 16:1-36

## ẸKỌ 58 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Nkan wọnyi si ṣe si wọn bi apẹ̃rẹ fun wa: a si kọwe wọn fun ikilọ̀ awa ẹniti igbẹhin aiye de bá" (I Kọrinti 10:11).**

**I Omi Mara**

1 Israẹli ni lati la aginju aṣṣálẹ̀ kọja ninu irin-ajo wọn, Ẹksodu 15:22
2 Omi ti wọn kọ́kọ́ ri kò dara fun mimu, Ẹksodu 15:23
3 Awọn ọmọ Israẹli fi ipo ẹ̀ṣẹ ti wọn wa han nipa kikùn si Mose, Ẹksodu 15:24; 14:11; Orin Dafidi 106:15, 16
4 Mose fi ẹmi Onigbagbọ́ ti o ni hàn nipa gbigbadura nigba ti won wà ninu wahala, Ẹksodu 15:25; Matteu 5:44
5 Nipa iṣẹ-iyanu kan Ọlọrun gba awọn Israẹl lọwọ oungbẹ ti i ba tu bọ maa gbẹ wọn siwaju si i, Ẹksodu 15:25
6 Ọlọrun fi aṣẹ ti o kún ati ilana kan fun Israẹli, Ẹksodu 15:25, 26; Jeremiah 7:22, 23
7 Israẹli pàgọ́ ni Elimu ni akoko kan, Ẹksodu 15L27

**II Manna ati Aparo fun Ounjẹ**

1. Ni aginju Sini awọn ọmọ Israẹli kùn si Mose ati Aarọni, Ẹksodu 16;1-3; 5:20, 21; 14:12; Orin Dafidi 105:40; 78:14-28
2. Ọlọrun ṣeleri lati ran ounjẹ lati ọrun, ki i ṣe lati pese fun aini wọn nikan ṣugbọn lati dan igbọran wọn wò, Ẹksodu 16:4, 5; Deuteronomi 8:3, 16
3. Ipese ojoojumọ yi tun fi han pe Ọlọrun ni Ẹni ti O mu wọn jade lati Egipti, Ẹksodu 16:6; Matteu 6:11; Filippi 4:19
4. Mose sọ fun wọn pe Ọlọrun ni wọn n kùn si, Ẹksodu 16:7-9
5. Ogo Ọlọrun fara hàn fun awọn ọmọ Israiẹli bi o ti n bá wọn sọ̀rọ, gẹgẹ bi ẹri siwaju si i pe Oun ni O n ṣamọna wọn, Ẹksodu 16:10-12
6. A ran aparo ni aṣalẹ, ati manna ni ni owurọ -- eyi ti o tó fun gbogbo wọn, Ẹksodu 16:13-15; Numeri 11:7-9; Jọṣua 5:10-12; Nehemiah 9:19-21; Ifihan 22:18
7. A fun wọn ni aṣẹ kan nipa manna ati pipa Ọjọ Isinmi mọ́ lati fi dan igbọran Israẹli wò, Ẹksodu 16:16-31
8. A fi ikòkò manna kan pamọ́ ni iranti titi fun ipese Ọlorun, Ẹksodu 16:32-36

## ALAYE

**A fi Iwa Ara we Iwa Onigbagbọ́**

Ayọ iṣẹgun nla ti Okun Pupa fẹrẹ ma ti kọja nigba ti wahala nla miran dide si awọn ọmọ Israẹli. Irin kiri awọn ọmọ Israẹli dabi igbesi-aye Onigbagbọ́. Nigba ti a ba bọ sinu awọn "iriri aginju" a n yiiri wa wò lati mọ̀ bi iwọn ibárẹ́ wa pẹlu Ọlọrun ti to ati bi imọ wa nipa ọkan awa tikara wa paapaa ti mọ. Akọtun igbadun ati ayọ nla ni o maa n bú jade ni ibẹrẹ igbesi aye Onigbagbọ́, eyi si le ri idojukọ ti o le lai pẹ; a fi bi a ba ni oye ti o fidi mulẹ ṣinṣin nipa ohun ti Ọlọrun jẹ́ fun wa, ki a si ni ipinnu ti o duro ṣinṣin ti o si rekọja ohunkohun, ki a si le foriti, bi bẹẹ kọ a o kuna, ati pe ninu ọkan wa, a o tun pada si Egipti.

Ekukáká ni omi ti ẹni kan le gbe lọwọ fi le to nkan fun lilo ni irinajo ọjọ mẹta laarin aṣalẹ. Lai ṣe aniani, awọn ọmọ Israẹli n fi gbogbo ọkàn foju sọna fun omi kinni ti wọn yoo ri lati mu lati fi pa oungbẹ wọn ati lati tu wọn lara. A le ri idi rẹ ti o fi ja si ijátilẹ nla fun awọn ọmọ Israẹli nigba ti omi ti wọn ri korò dipo pe ki o dùn. Iyiiriwò kan ni eyi jẹ fun wọn. Ọlọrun ha n ṣe Ọlọrun wọn ni tootọ́ bi? Oun yoo ha tọju won ninu gbogbo ọna wọn bi? Awọn iṣẹlẹ ti o tẹle eyi fi kikuna wọn ati aini igbagbọ wọn hàn.

**Omi Kikoro Tabi Isun Omi Didùn**

Wo iyatọ ti o wa laarin awọn ọmọ Israẹli yi ati Mose ẹni iwa-bi-Ọlọrun. Wọn n kùn si Mose wọn n ba a sọ̀; ṣugbọn o kigbe si Oluwa. Nihin ni a ri ifarahàn iyatọ laarin ẹni ti ara ati ẹni iwa-bi-Ọlọrun. Ọkan kún fun irahàn, ikoro ọkan ati aimoore; ṣugbọn ekeji kò ni ọkan ninu awọn iru iwa bẹẹ ninu ọkan rẹ; nitori pe o ni Isun kan ti ki i gbẹ. Orisun agbara ati atilẹhin ti i ṣe ti rẹ nigba gbogbo, ati Eti kan ti ki i tì si igbe rẹ. Omi kikoro yi jẹ aworan iyiiriwò, idanwo, ibanujẹ, irora, ọ̀fọ̀ ati adánù aye eyi ti o n de ba gbogbo eniyan. Ṣugbọn Onigbagbọ́ ni Ẹni kan ti o le tọ̀ lọ fun idasilẹ ati itunu.

Ajalù ti n mú ibanmujẹ ba ni le tẹle ayọ iṣẹgun ti o ga ju lọ, bi lila Okun Pupa kọja ni igbesi-aye ẹni bi o tilẹ jẹ pe a n rin sibẹ loju ọna titọ́. Ṣugbọn lẹba omi Mara kọọkan ni igi kan n hù, eyi ti yoo sọ omi naa di didun ati didara

nigba ti a ba ju u sinu rẹ. igi kan? Ni tootọ́ ni; ṣugbọn igi kan ti ko ni ewe ni, ti a gé jákujàku, ti igba ati akoko ti pa lara – Agbelebu nla nì ti o ṣọwọn, ti ibanujẹ ati ti iyanu ti Ọmọ Ọlọrun. Ni ipasẹ itoye Etutu ti a ṣe lori Agbelebu a le ri iranlọwọ ti a n fẹ ninu wahala aye. Igi yi ti Oluwa fi hàn fun Mose jẹ aworan daradara ti awọn ibukun ti Kristi, ni ipasẹ Agbelebu, itiju, ati ajinde Rẹ̀ ti o tẹle e, maa n mu wa sinu igbesi-aye ẹni ti o ba gbagbọ́. Igi nì tikara rẹ ko ni agbara iwosan kan ninu rẹ, gẹgẹ bi amọ̀ ti Jesu fi lẹ oju ọkunrin afọju nì, tabi omi odo Jọrdani ninu eyi ti a wẹ ẹtẹ Naamani mọ́ kò ti ni agbara iwosan kankan ninu. Jiju igi naa sinu omi naa jẹ lilò ati fifi igbagbọ́ ati igbọran ti o maa n mu esi rere wá hàn.

**A Fun Wọn Ni Ofin Kan Ṣiwaju Ofin Mose**

Ọlọrun ṣe ofin kan ati ilana kan ni akoko yi fun anfaani Israẹli ati iṣamọna wọn, ninu eyi ti ipilẹ iwa rere gbe wà ti o ti wà lati atetekọṣe gẹgẹ bi o ti wà ninu Ofin pẹlu ti a fi fun ni lori Oke Sinai (Ẹksodu 15:25, 26). Fifun ni ni Ofin lori Oke Sinai jẹ iṣisẹ kan siwaju si i ninu eyi ti ninu eyi ti Ọlọrun n fi ara ati ifẹ Rẹ̀. hàn Ofin yi, ti a fi lelẹ ṣiwaju ki a to tẹ́ pẹpẹ akọkọ ni iju, jẹ eyi ti o niye lori lọpọlọpọ gẹgẹ bi eyi ti n fi ohun pataki ju lọ ati ẹmi ilana Ofin Mose hàn. A fi I lelẹ pẹlu ileri fun ẹni ti o ba pa a mọ pe eyikeyi ninu arùn Egipti ki yoo wá si ara rẹ, ati pe Ọlọrun yoo jẹ Oluwosan rẹ, ati pẹlu pe yoo jẹ amọna ati alaabo fun un. Eyi jẹ ọkan ninu awọn ileri nla wọnni ti a duro le lori nigba aisan ati iyiiri wò.

**Irin-Ajọ Lọ si Aginju Sini**

Israẹli pagọ si Elimu nitori pe kanga mejila ati aadorin igi ọpẹ wa nibẹ. Arinrin-ajo kan ti n wadi nkan ti o si jẹ olufọkansin lai pẹ ri ibi ti o gbagbọ pe wọn tẹdo si yi. O ni mẹsan ninu awọn kanga naa wà ni ṣiṣi silẹ sibẹ, bẹẹ ni iyanrin aṣalẹ naa kò da isun omi wọn duro. Awọn aadọrin ọpẹ naa ti di igbo ti n mu ere ti o ni laari wa fun awọn ti wọn n kore eso wọn.

Ṣugbọn awọn ọmọ Israẹli tún kùn! Ni akoko yi wọn kùn si Aarọni pẹlu. O dabi ẹni pe awọn ọmọ Israẹli gba mimu ti a mu won jade ni ilẹ Egipti si iṣẹ ọwọ́ Mose ati Aarọni. Iṣẹ-iyanu naa si ja si eyi ti o n mu ni lọkan ṣinṣin, ṣugbọn lẹsẹkẹsẹ ti wọn ba ti kọja, awọn ọmọ israẹli a tun pada si aigbagbọ́ wọn atijọ. Nitori naa Ọlọrun fun wọn ni iṣẹ-iyanu lojoojumọ ki wọn baa le ri ẹri pe ọwọ́ Oun ni o wà nibẹ nigba gbogbo niwaju wọn. Yatọ si ipese aparo ni ọna iyanu O tun fun wọn ni manna lojoojumọ fun ounjẹ wọn.

Gbogbo ọrọ̀ wọn n fi hàn pe wọn fẹ lati wà ninu igbekun wọn ni Egipti ju lati wà ni ipo ti wọn bọ si ni akoko yi bi o tilẹ jẹ pe ileri ilẹ alaafia nibi ti wọn yoo ni anitó lọpọlọpọ wà niwaju wọn. Ko le jẹ pe wọn kuku wà ninu aini patapata, nitori pe pẹlu ọpọlọpọ ọwọ́-ẹran ati agbo ẹran ni wọn jade ni Egipti. Igbe wọn si Mose ati Aarọni, “Awa i ba ti ti ọwọ OLUWA kú ni Egipti,” fẹrẹ le fihàn pe wọn yàn lati kú ninu ọkan ninu awọn ajakalẹ arun ti a ran sori Egipti, ju ipo ti wọn wa yi lọ. Ninu aini suuru ati aigbagbọ́ wọn, wọn n jowu iru ipin ti o de ba awọn aninilara wọn ti a ti parun! O ṣoro fun ni lati gbagbọ́ pe iru ọkan aimoore ati igbagbe oore-ọfẹ Ọlọrun ati agbara Rẹ̀ le ṣẹlẹ si wọn bayi, ṣugbọn bi a ba yẹ ọkan wa wo awa naa le ri iru ohun ti i ba wa ninu rẹ bi ko ṣe ti oore-ọfẹ Ọlọrun!

**Aigbọran Israẹli**

Fifun ti a fun wọṅ ni manna paapaa jẹ lati yiiri igbọran Israẹli wò. Ni owurọ, iwọn ti yoo to fun ounjẹ won ni ọjọ kan ni wọn ni lati kó, oṣuwọn omeri kan fun ẹni kọọkan (**omeri** kan to iwọn quart mẹta ninu iwọn, eyi si n tọka si **okiti** kan). Ni ọjọ kẹfa wọn ni lati ko iwọn kan le fun Ọjọ Isinmi niwọn igba ti ki yoo si manna ni Ojọ Isinmi yi. Manna ti a ba ko silẹ ni ọjọ lasan di ọjọ keji yoo yọ idin, ko si ni dara fun jijẹ, ṣugbọn eyi ti wọn ba kó ni ọjọ kẹfa yoo jẹ titun sibẹ fun Ọjọ Isinmi. Oorun yoo yọ́ manna ti o ba ku ni ori pápá lẹhin ti wọn ba ti ko eyi ti wọn yoo jẹ, sibẹsibẹ a le din manna yi gẹgẹ bi a ti maa n ṣe akara fun jijẹ. Pẹlu iri ni o n sọkalẹ, sibẹsibẹ o le to bẹẹ ti wọn le lọọ lori ọlọ tabi ki won gun un ninu odo.

Gbogbo eto wọnyi lẹsẹẹsẹ ni a ṣe lati fi kọ́ Israẹli ni ẹ̀kọ́ nla. Ki i ṣe pe wọn ṣe alai le gbẹkẹl;e Ọlọrun fun ipese ounjẹ wọn nikan, ṣugbọn wọn ti gba ounjẹ yi gẹgẹ bi ohun pataki ti wọn tori rẹ wa laayè; nitori naa Ọlọrun rẹ wọn silẹ O si fi ebi pa wọn, O si fi ounjẹ ti wọn ko mọ̀ ri bọ wọn, ki wọn baa le mọ̀ pe eniyan ko wa laaye nipa ounjẹ nikan, ṣugbọn nipa gbogbo ọ̀rọ ti o ti ẹnu Oluwa jade wá.

Ẹkọ akọ́kọ́ ni ti gbigbẹkẹle Ọlọrun lojoojumọ fun aini wọn. Jesu kọ awọn ọmọ-ẹhin lati gba Adura Oluwa ninu eyi ti o ni ki wọn beere ounjẹ oojọ wọn. Ọlọrun n fẹ ki a gbẹkẹle Oun fun ohun gbogbo – ni igba gbogbo! A jẹ alagbara nigba ti a ba mọ ailera wa ti a ba si tọ Ọ wa fun iranlọwọ.

Ẹkọ miran ni igbọran. Awọn kan laarin wọn fi ainaani aṣẹ Ọlọrun hàn ati aigbẹkẹle Ọrọ Rẹ̀, won si tun fi iwa wọbia ati ojukokoro hàn nipa ki kó ju eyi ti a palaṣẹ fun wọn pe yoo tó fun ounjẹ ọjọ kan lọ, ati nipa jijade lati lọ kó manna ni Ọjọ Isinmi. Aigbọran wọn fa ọ̀rọ idalẹbi lati ọdọ Ọlọrun, ni aisi iyemeji, aanu Rẹ̀ nikan ni O fi fa ọwọ́ Rẹ̀ sẹhin ti ko fi ké wọn kuro ninu ẹ̀ṣẹ wọn.

**Ẹnikẹni ti O bá Fẹ́**

Ifarahan ipese Ọlọrun ojoojumọ yi jẹ apẹẹrẹ itú-jade ibukun ojoojumọ ti Ọlọrun n ran si awọn ọmọ Rẹ̀, eyi ti o jẹ ẹ̀kọ́ nla fun wa. Manna yi jẹ apẹẹrẹ Kristi, Ọrọ Ọlọrun. Jesu ni Oun ni ounjẹ Iye. O sọkalẹ wa lati ọrun lati fi iye fun gbogbo awọn ti yoo gba A gbọ́ ti wọn yoo si gbọran si aṣẹ Rẹ̀. Bakan naa si ni a ni lati maa kó ounjẹ yi

lojoojumọ bi a o ba ri anfaani lati inu rẹ. Awọn ọmọ Israẹli i ba kú ninu aginju bi ko ba ṣe pe Ọlọrun fi ounjẹ lati ọrun wa bọ wọn, bẹẹ ni gbogbo eniyan i ba ṣegbe bi ko ba ṣe pe Jesu ti ọrun sọkalẹ wa o si fi ara Rẹ̀ fun iye araye. Manna ti o tó wà fun gbogbo eniyan (Ẹksodu 16:18); bẹẹ ni ipe nla ti Ihinrere, "Ẹnikẹni ti o ba fẹ" fi idani loju lati wọ̀ inu iye-ainipẹkun fun olukuluku ọkunrin, obinrin ati ọmọde ti yoo tẹwọ gba iṣẹ-iyanu ti oore-ọfẹ.

Ibukun ti a ri gba ni owurọ jẹ ere gbogbo ọjọ naa jalẹ. Nigba ti eniyan ba bá Ọlọrun pade ni owurọ, ki o to doju kọ aniyan ati ẹ̀rù ọjọ naa, o ti ba ire pade o si ti ri ibukun gba ti yoo ni jalẹ gbogbo ọjọ naa. Bẹẹ ni eto ọjọ kan ninu aye wa jẹ bakan naa pẹlu eto gbogbo ọjọ aye wa. Bi a ba wá manna ti ọrun ni kutukutu ọjọ aye wa, gbogbo akoko ti a yàn fun wa ni aye yoo kun fun ibukun eyi ti yoo pari si ipalarada ologo ni Ile wa ayeraye nibi ti a o gbe gbadun Oluwa ati Olugbala wa laelae.

## AWỌN IBEERE

1. Ibukun wo ni a ni lati nireti ti a si le ri gba lati inu "iriri ti aginju?"
2. Iwa wo ni Israẹli hù nigba ti wọn ri i pe omi Mara kò dara fun mimu?
3. Kin ni Mose ṣe? Kin ni a ti ṣe le mu apẹẹrẹ rẹ yi lo ni igba isinsinyi?
4. Sọ gẹgẹ bi a ti wi i gan an tabi ki o sọ ni ọrọ ti rẹ ohun ti o wa ninu ofin ati ilana ti a fun Israẹli ni akoko yi.
5. Ileri nla wo ni o wà ninu ofin yi?
6. Nigba ti Israẹli tun kùn, tani wọn ro pe awọn n kun si? Tani wọn si n kùn si gan an?
7. Kin ni idi rẹ ti wọn fi n sọ̀?
8. Bawo ni Ọlọrun ti ṣe dahun si i?
9. Darukọ awọn ohun ti o wa ninu ẹ̀kọ́ Bibeli yi ti o n fi hàn wa pe ọna iyanu ni a fi gba mu manna yi wa?
10. Ẹkọ́ nla nipa pipa Ọjọ Isinmi ati bibọwọ fun un wo ni a kọ́ wa ni akoko yi?